# AGBA SỌ OTITỌ O DI ẸNITI IYA NJẸ

Aiye toto ile aiye ile asan ọmọ nba baba rẹ ṣe igberaga, baba sọrọ ọmọ ko gba asẹhnwa asẹhinbọ baba ni ọmọ araiye nfi iya je nitori ọmọ rẹ otitọ koro ile ofotitọ ni Ọlọpa inu nwa kiri, Ika di ọga ilu daru omo to kọ ohun baba rẹ ati ọmọ pe omo ni lati ko ohunti on na.

Bi aiye tilẹ ngbe oṣika o daju pe nwon nbo wa ti si koto lola. Baba ti omo rẹ nṣe buburu ti ko so fun iku omo na yio pa baba Ṣe ẹnyin ti gbo iran Eli nigba aiye rẹ tabi awon omo ti ko wulo ni ojo kan nile Eli parun.

Bi Ẹlẹṣẹ ba njiya, olododo yio jẹ nibẹ nitori pe ẹnikẹni ti o ba safun enia ti o duro de Adakẹdajo iya ilopo meje ni yio jẹ.

O san lati jẹ kekere iya nigbati iwo ba so otito ju ki o pa enu rẹ mo nigbati atunṣe si wa jẹ kekere iya ki o ma ba jẹ nla. Bi a tilẹ nje olotito niya sibesibẹ awon ti omo otito yio mo wipe iya ni a fi nje olotito. O da mi loju pe Ẹlẹṣẹ ki yio le laijẹ iya

Ohun gbogbo lo ni akoko tire, eniti o ba ma je oba lati lo si odo ijiya nla . i evi jẹ fun won Bi o wu ki Ọba ti pẹ to ni odo ko si eniti o le ṣe bi Ọba paapa julo gbogbo enia ni yio mo wipe Ọba awọn wa lodo ko ti de

Ijiya gbeniga ni oruko awon olọla, tani enyin yio fi ṣe akawe re tabi tani eniti o toju re da ofurufu, iy. nu ni oruko baba mi

## Omo To Lu Baba Rẹ

Iwọ ika ti o bi ọmọ tirẹ silẹ ti o si ngbeja ọmọ elomiran pe ki ọna baba tirẹ ni ṣoju ẹmọ tirẹ ra nti pe ẹsan re ajo o nbo nile opẹ o ka ẹran ni lati de bi ẹnyin ko ti lẹ si ni aiye ṣebi ẹ gbọ nigbati Farao paṣẹ fun gbogbo awọn enia rẹ wipe gbogbo ọmọ kunrin ti a bi on ni ki ẹnyin gbẹ ju sinu opo gbogbo awọn ọmọ binrin ni ki ẹnyin ki o da si.

Nitori mose kọ yi bi lemeji ẹsan ke nitori Mosẹ na ti a ran, Oluwa yio si pada si agbedemeji ẹran osin Israeli ati ẹran ọsin Egipti ko si ohun kan ti yio ku ninu gbogbo eyiti iṣẹ ti awọn ọmọ Israeli Oluwa sida akoko kan wipe ni ọla ni yio ṣe nkan yi ni ilẹ yi o si ṣe gbogbo ẹran Egipti si ku ṣugbon ẹran ọsin ọmọ Israeli ni nka nkan ko ṣe.

## Aiya Farao Si Le

Oluwa si wi fun Mose pe Farao ki yio gbọ tirẹ ki a le so iṣẹ iya nu mi di pupọ ni ilẹ yi awọn ọmọ Israeli si lọ nwọn si ṣe bi Oluwa ti fi aṣẹ fun Mose ati Aaroni bẹn, nwọn ṣe latin ọganjọ ni Oluwa pa gbogbo awọn akọbi ni ilẹ Egipti

Lati akọbi Farao lọ ti o joko lo ri itẹ rẹ titi o fi de akọbi ẹru ti o wa ni tubu ati gbogbo akọbi ẹran



**Ọmo Oba Adakẹdajo**

ọsin ariwonla si ta ni Egipti

O si ṣe nigbati Farao jẹki wọn na ki o lọ ran awọn omo Israeli jade lọkuro ni ilẹ Egipti ni ibamo ra Mose si gbe egungun osefu lo pelu re enit i iṣe olugbnla Israeli.

Nwọn ko lati fi balẹ fun, ṣugbọn nwọn fi ori balẹ fun ni ajeji nitori ibura lile ti awọn ọmọ Israel dupe l'oto ni Adakẹdajọ yio yio da ẹjọ nyin ki ẹnyin ki o si ru egungun mi lo pẹlu nyin kuro nihin.

E se ti awa fi se eyi ti awa fi jẹ bi Israel ki o lo kuro ni sisi wa Nigbati Farao si nsunmọ tosi awọn ọmọ Israel gbe oju soke nwon ri Farao pẹlu ogun rẹ nbọ lẹhin

**Ẹ ma a Ka Iwe Irohi Imọlẹ Ki ẹ si ma a Polowo Oja Nyin Sinu rẹ Lojojumo**

Mose wi fun wọn pe "Ẹ ma bẹru ẹ duro jẹ ẹ ki ẹ si ri igbala Oluwa ti yio fi han nyin ni oni ni tori awọn ara Egipti ti ẹnyin ri ni oni yi ẹnyin ki yio siran ri won mo lailai.

## ILẸ MA BẸRU

Oluwa yio ja fun nyin ki ẹnyin ki o si pa ẹnu nyin mo Oluwa si wi fun Mose pe na ọpa rẹ si oke ki iwo si na ọwọ rẹ si oju okun ki o si ya a meji awọn ọmọ Israeli si kọja ni alafia Mose si na ọwọ re si oju okun, okun bi pada bo si ipo rẹ nigbati ilẹ mọ awon ara Egipti si sa lu Oluwa si bi awon Egipti subu larin okun

**Lati Owo Omo Oba Adakedajo**

Otito ni mo wi fun nyin esan ki ke fori ọba Farao ti o pa aṣẹ peki a -a ọmọ kunrin ni Ilu Ifaidu ni tori Mose nikan sosio Oluwa san fun won nigb. meje ni ikehin Farao pẹlu ṣegbe pelu ogun re Tani ọba alade ti ko le pada di eranko

O digba diẹ e o tun ma gbo iyoku laipẹ y o


BERE FUN OJULOWO ADI _ELEGB

# "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atamataṣe ni egbogi "ADI-ELEGBO" yi i fun itoju ebo ebo orisirisi "EGBO—EṢẸ" ni kiakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni egbẹ nipa wipe awa ko idọti ti bi ẹri gbogbo ti o ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lehinna oju egbo ti o ba jin sinu yio jeki oju re ru wa soke, y o si pọn daradara arun bakiru ko si mọ werewere ni yio si san pata pata, Alafia de si ọ niyen : –

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Eleru tabi onijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba a ra o.

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787

# OLUMOFIN F ERE BEE NIGBATI EMI REWALEWU

IKARE:- Ogbeni D. K Olumofin siyan ko doro gba gbe nigbati o fi oju kan awon wonpari enia ti oju nwon ko se wo rara ti nwon tun mu ada, kumo, afo cu igo, ibon ati awon okan ija ogun lowo nwon, ti nwon beresi ko orin owe ati orin ija ti eniti o ba ri wo osi fun emi re ni.

Onirohin wa fi ye wa pe, ni opin ose t lo ni Ogbeni D K Olumofin pelu adajo ibile Ikare iij wa ninu moto Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria ti nomba re je (W N G 5) bi awon ti o nwode kiri ti f o j u k e fi Ogbeni Olumofin ni enikan dahun ninu nwo pe, eerun nrun, ni awon enia ba nwa kiri.

Bi Ogbeni Olumofin ti fi oju ganni awon opo enia, bi idan ni o ba fi ese fe e ni nwon ba gb ya won, nwon le won tiri ti owo fi te Ogbeni Olumofin ati eni ti o nwa moto re, nwon le won ni inakuna to fi je pe ile-ogo ni o gba won ate bayi.

Ni won ba dana sun moto ti awon wo, moto na si jona di eeru patapata.

Irohin tun fi ye wa pe oba ilu Ikare ti lo si Owo bayi fun igbala emi re ile meta-la ni nwon sun ninu ilu Ikare pelu ile okan ninu og Olopa ibile fun agbegbe wo Ghogbo awon ile na ie si awon omo egbe Demo

Ki awon enia yi to bero si ma a se ise ibi na ni won ti lo be igi ni di ona ti o wo ilu Ikare bi awon olopa ba rbo wa lat pana ija ti o nlo nwon ki ri aye lati wo ilana titi ti nwon yio jo ile nsati moto ti nwon fe jo tan ti ko ni si eniti yio da won lowo ko



Ogbeni D. K. Olumofin

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS Jan 22 Feb 20 Oj oni ate ironu ti o jinle lati odo re, nitorina o ye ki o siju wo iwaju ki o to be siwaju, ki o si sora nitori afojudi re

PISCES Feb 21 May 20 Ailera yio da o lima die loni sugbon bi o ba lo ogbon die si iwo yio yege

ARIES (Mar 21 - April 20) Fi okan si ise ti o nse ni ojojumo awon eni rere ni yio si rogba yi o ka ki a si ma soro eni ni rere si ara eni ni yio sanfani

TAURUS (April 21 May 20) Bi o ba je wipe iwo ni o nsaba gba ohun ibi ise pin ise na fun awon elomiran bi o ba si ngbero lori ohun kan jeki o je didun inu awon enia re

GEMINI (May 21 June 21) Ajumose iwo pelu awon elomiran ko le suwon nitorina ki o so gbolohun oro ti o njade lenu re ki o ma ba di ijogbon.

CANCER (June 22 July 22 Are yio mu o loni mase ba awon onirego wiregbe oro kan loni,

LEO (July23 Aug 22) D oko pataki meji yio gunle si okan odo re kini lenu ise ati fun iwo alara papa pataki ti o wa nibe ki o so ara re re jojo

VIRGO (Aug 23 Sept 23 Nse ni ki o ronejinle daradara ki o to se ise wo kan ni akoko owuro yi, ki o si la oju re sile lati ma fi ri awon ohun ti o nkoja lo

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Idera ati alafia yio mirin gindin i odo re loni eru re yio si ranle lori awon elomiran

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Bi iwo ba lero lati re oja ka lo nse n ki o rju sile, ki o wo wajibu ya tabi ere jije mbo ni ibomiran

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) So ara re gidigidi, ki o si toju alafia ara re

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) B ojo ti ana bani ani yio ri, ki o ma b jeki iwa alero gbe o si nu iyonu ati ijogbon, oju ni kan fi nso ori

Gegebi irohin kan ti a tun ri gbo lati ilu Agege ni ekun Ekiti papa fi ye wa pe gbogbo awon omo egbe Demo pelu iyawo ati omo nwon lo ti fi ilu sile patapata ti enikan ko si le so pato ibiti nwon wa doni awon ti o si ku nile ti ni awon ti yowo yose kuro ni nu egbe Demo awon ko si ni tun sna de inu egbe Demo mo nitori a awon t pada si egbe Afenifere ti won ti wa ri

Irohin ati ilu Ibese ni ekun Egbado fi ye wa pebe si titun gb na girigiri bayi Ogbeni kan ti onje Baba Ibese ni o fi ara gb gbe ni gbati ija be sile ti ija na di eni aba ni a nlu opolopo ile ni nwon tun dana sun nibe pelu iroin na tun fi ye wa pe gbogbo enia ti wa ni ilu ilu Ibese to ti fi ilu sile bayi.

Ibese atijo ti fere di aho ro tan bayi fun jijo ti nwon njo ilu na ni igbagbogbo.

Awon olopa ti lo si Ibese bayi lati le jeki alafia ti ifokanbale le wa nibe a siti gbo pe awon olopa ti mu

awon kan ti nwon fura si pe nwon le lowo ninu ija igboro ti o be sile na.

Ni ilu Ilesha ni nwon ti tun sun oko omo egbe Demo kan di eerupatapata ni biti o gbe si ni agbegbe kan ti o nje Iroye ni Ilesha ti uwon eniti nwa moto na ni ogbe ni gbogbo ara o si wa ni ile oogun ni Ilesha bayi ti on nwa ni igbo elege

Ni opopo Okesha ni Ilesha ni nwon tun sun moto nla kan di eeru bayi ti won tun sun Ijoye kan di eeru patapata awon omo Demo meji Ogbeni Ilesanmi ati Toye lo wa ni ile oogun ba yi nigbati nwon fe gbija egbe Demo ni opopo Iloro ni Ilesha

# LILO ORUKỌ ENIA NI ỌNA IDABOBO

MOSCO:— Ni opin ọsẹ ti o kọ a lọ yi ni Iwe Irohin kan ni orilẹ ede Rọsia ṣe alaye Irohin kan wi e, awọn Iwe Irohin ojoojumọ ati awọn Iwe rohin ọsọsẹ ati oṣoṣu nfi aworan eke kan han ninu Iwe Irohin wọn wi pe agbelebu ti awọn gbe si igba aiya okunrin na ni ti agbelebu Hitler

Iwe Irohin na tun ṣe ala ye siwaju pẹlu wipe, nigba ti nwọn ya a oran na nwọn gbe agbelebu kan ka igba aiya ọkunrin, nwọn si ṣe apejuwe rẹ gẹgẹbi agbelebu Hilter, ẹniti o da ogun ajakaiye Keji silẹ, eyi ti wọ ja yika gbogbo agbaiye ninu ọdun 1939 ti o si pari ninu ọdun 1945.

Nigbati awọn ayaworan ya aworan ọkunrin na nwọn de fila kan ti nwọn npe ni fila Bẹrẹti fun un, nwọn wọ ṣokoto kaki pepe kan fun un nwon si gbe agbelebu kan si igba aiya re.

Gẹgẹbi irohin na ti a ri gba, a gbọ pe Bieghied ni orukọ ọkunrin na ti nwọn ya aworan rẹ ti nwọn ṣe ohun ọṣọ si lara ti nwọn npe ni Hitler.

Gẹgẹbi irohin a gbọ wipe ọkunrin na jẹ ọkan ninu awọn ti nwọn nki awọn enia orilẹ ede Kongo laiya lati le ṣe ohunti nwon ti nṣe lori rudurudu ati rogbodiyan to nṣẹlẹ yika orilẹ ede na.

Nigbamiran, ọkunrin na a ma ṣe ifojukoju ati awọn enia lati ma sọ ọrọ ti wọn jọ nsọ nigbati oju ba kan oju.

## IBERE

Ọkan ninu awọn oniwe irohin ni orilẹ ede Jamani bere ọrọ lọwọ ọgbẹni Siefg ried Muller bi igbesi aiye awọn ọmọ enia t'ṣe ri ni orilẹ ede Kongo.

Ṣugbọn si ibere yi, ọgbẹni Muller dahun pe enia le nri ọti, ni Kongo enia le jo bi o ba ti wu u ki o si ṣe ohunti o ba fẹ pẹlu ... idiwọ,

Bakanna ẹwẹ ni o tun ṣe alaye wipe enia le lọ sn abẹwo Ile ẹkọ kan ti nwọn npe ni "GOETHE" bi enia ba fẹ

Oniwe Irohin na tun bere lọwọ Muller bi o ba de ile iṣẹ na eyiti o wa ni orile ede Kongo ati bi o ṣe si ti ṣe gbadun ibere na to, ati awọn ẹga oluko agba ti nwon wa ni Ile ẹkọ.

Si ibere yi Ọgbẹni Mi- sọ pẹlu ikanju wipe "Mo de Ile ẹkọ na mo gba dun iṣẹ ti awọn nṣe eleyi nikan tile si kọ kodo nigbati mo de ibẹ mo fi dara wọn ṣere die mo si tun fi duro na kọrin ki nto kuro nibẹ ni ọjọ na pẹlu.

Lẹsẹkẹsẹ ni o tun fi idahun kan jẹ omitoro ọrọ pẹlu awọn oniwe Irohin na wipe on ki iṣe ọkan ninu awọn ti nwọn nṣe iku pa awọn adulawọ ti nwọn wa ni Orilẹ ede Amẹrika

Irohin kan tun ṣe alaye pe ninu ọdun 1932 ni wọn da ile ẹkọ Goethe silẹ ni orilẹ ede Iwọ Orun Jamani nibiti nwọn gbe nkọ ede ijinlẹ Jamani nigbana.

Ṣugbọn ni asiko yi, nṣe ni nwọn nran awọn ọmọ ile ẹkọ na lọ yika gbogbo igun mẹrẹrin aiye lati tun ma lọ kọ ede ijinlẹ awon orilẹ aiye mi an ile ẹko na lo jẹ eyiti o tobi julọ ni ori lẹ ede Jamani nigbana

Ninu ile ẹkọ yi ni nwọn ti nkọ gbogbo awọn ede agbaye ti nwọn si tun nkọ awọn kan ninu awọn ọmọ ile ẹkọ na ni ojulowo wọn ti nwọn ṣe le mu ri alekun ati ilọsiwaju ninu ọja wọn.

Ẹniti o kalọ jẹ ọga agba ninu ile ẹkọ na ni, ọgbẹni Karl Houshofer, ẹniti iṣe ọkan ninu awọn to ni imọ ijinlẹ ọgbọn ati oye nigbana ti nwọn npe ni "Geobo litik" to si tun jẹ ọrẹ korikosun ọgbọn Alfred Rose nberg.

Ile ẹkọ yi di ohunti awọn da silẹ yika gbogbo aiye ti nwọn si nkọ awọn enia ni onirẹru ede nibẹ ki iṣe ede Jamani nikan ni nwọn nkọ wọn ṣugbọn awọn ede miran pẹlu ti o jẹ ti awọn ijoba alaṣbara oril ede aiye

Ọkan ninu awọn ọgbọn igbana ti nwọn nkọ awọn ọmọ ile ẹkọ na ni iwe ti Dọkita Hans Grimm ati Goide Kolbeahene Dokita Goebbels. Awọn yi tun jẹ ọrẹ olori ile ẹkọ na nigbana eyi lo si fun wọn ni anfani lati wa nib

Ṣugbọn nigbati ogun pari ninu ọdun 1945 ni Ijọba Amẹrika ba paṣẹ wipe ki nwọn ti Ile ẹkọ na pa patapata wipe awon ko tun fẹ ma a gburo rẹ mọ

Sibẹsibẹ fun igba di ni Ijọba Amẹrika le jẹki nwon ti Ile ẹkọ na nitori pe nwon tun nkọ won ni iṣẹ Ṣọja ninu ile ẹko na ati bi nwon ti ṣe jagun agun

Nigbati o si di nu odun 1952 ni nwon ba si Ile ẹko na pada ti nwon si tun bẹrẹsi ko awon omo Ile ẹko na ni iwe won gẹgẹbi ti atẹhinwa

Ṣugbọn nigbati awọn Ijọba Amẹrika si ile ẹkọ na pada nigbana nṣe ni nwọn wa lọ ko awọn ọmọ ilẹ Amẹrika wa lati ma ṣe iṣẹ olukọ nibẹ ẹniti nwọn si yan ni olori ile ẹkọ na ni Dọkita Max Grasaman ẹni ti iṣe ọmọ ilẹ Amẹrika.

Lẹhin na ni nwọn wa tun yan awọn kan gẹgẹbi Igbimọ alamoju o awọn eto ile ẹkọ na nwon wonyi ni Ijọba ni ki nwọn ma ṣe eto fun ilọsiwaju ati idagbaso ke Ile ẹkọ na

Ṣugbọn nigbati awọn ọmọ ile ẹkọ lọ sile Monter video lati lọ ba awọn kan gba bọọlu nwọn ba riwe kan ninu iyara ti nwọn gb... fẹ ninu danu eyiti nwọn ti de daru ninu ... ki won mẹṣe fun won ni own

Ko pe lẹhin eyiti ọgbẹni Adib Leniyami ti so pe ki nwon ti ile ẹko na eyi towa ni Damasku nitori iwa gbe legoida ti awon enia na nhu

Lẹhin eleyi ni Ọgbẹni Muller tun ko ile iṣẹ kan si orile ede Kongo, o si nṣe awon enia ni ijamba ti o tun ṣe ohun ikoko abẹ l eyiti nwon so wipe o lo di si ofin


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYNAMREN** TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọnki amonu tilun ti gbogbo aga Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akrbara ati Agbidan iṣẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lasan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi jube lọ mọ daju pe DYNA MIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di , tun patapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada kAra rẹ yio gbe kankan ni gugba yio san pẹlu ioq eduubrode iyẹn dij bi



WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria. (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

NIGERIAN MEDICINE STORES
4. Tinubu Square Lagos

ATI NI ṢOBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE
IBADAN

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,578 MONDAY DECEMBER 6, 1965 (2D)


## Awọn Olori Ẹgbẹ Dẹmo Mushin Pada S'Ẹgbẹ Afẹnifẹre

MUSHIN:— Lati nkan bi ọsẹ mẹta sẹhin ni irohin ti nde si ile iṣẹ wa fun akọsilẹ awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ ati awọn ọmọ Ile Igbimọ ti Ijọba ibilẹ pẹlu awọn Adajọ ninu ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ ti nwọn nbinu fi aye wọn silẹ ti nwọn si tun nkuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre 'ori iwa jibiti ti ẹgbẹ Dẹmọ hu lori ibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti awọn ẹgbẹ Dẹmọ fi eru ṣe pe awọn lo bori ibo na.

Ninu irohin to tun de ọwọ wa ni owurọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni irohin lati ọwọ Akọwe eto itankalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre fun iha Gusu Ikẹja Ọgbẹni J. A. Abati pe on ti ri iwe gba lati ọwọ Oloye Asani Ọlajoku, Ekerin ti ilu Waigbo Mushin eniti adape rẹ tun njẹ "Ekute ile paramọ" ti binu fi ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) silẹ pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Naijiria.

Bakanna ni Oloye Asani Ọlajoku tun kọ iwe si Adele Akọwe agba fun eto itankalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni Lawanson Bakanna ni Oloye Ọlajoku tun fi ẹda iwe ti o fi kuro ninu egbe na ranṣẹ si Oloye L. A. Oluwa ti o jẹ olori egbe Afenifere ni ilu Mushin ati Ọgbẹni G O Akanro ti iṣe Alaga egbe Afenifere ni ilu Mushin.

# IJỌBA CZECHOSLOVAKIA

### Lati Oju Ewe Kini

Lẹhin ọpọlọpọ alaye ati iṣ ọrọ we ọrọ ni Oloye Okotie Eboh w fi owọ si iwe adeh n na, eyiti Ijọba yio fi ya Naijiria ni owo (£5,000,000)

Nigbati nwọn pari iwe adeh n yi tan, Oloye Okotie Eboh tun fi ẹsẹ kan de awọn Orilẹ ede ilẹ Okere miran ti nwọn tun wa ni awọn agbegbe na lati tun ṣe a on iṣẹ miran ki o to pada wa si ile

Oniwe Irohin wa kan fi ye wa wipe, ni ilu Czeckoslovakia ni Oloye Okotie-Eboh gbe ti kọ Iwe rẹ pa i nigbati o fi lọ si ile ẹkọ giga, o si ni ọpọlọpọ awọn ọrẹ ati ojulumọ enia inu ilu na pẹlu.

Bakanna ẹwẹ ni oniwe Irohin wa kan ran wa leti pe, ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu k jọ ọdun yi, ni Ọlọla Dokita Otak Liska, Asoju Ijọba orilẹ ede Czechoslovakia ni Naijiria ṣe ibẹwo lọ si ile iṣẹ Dokita K O. Mbadiwe, Minista Alamojuto eto owo fun Apapọ Ijọba Naijiria.

Ọlọla Dọkita Otaka Liska ṣe al ye nigbana wipe, Ijọba on yio ṣe iranlọwọ adotaler gba ọ k ẹ pọnun (£5 000,000) fun orilẹ ede Naijiria, f iṣẹ Aje ati idagbasoke.

Dokita Otaka tun ṣe alaye nigbana wipe, o le ni ogorun (100) ọmọ orile ede Czechoslovakia ti nwọn wa ni Sapẹlẹ, nibiti nwọn gbe nṣe bata.

O tun ṣe alaye pe, awọn enia na ti bẹrẹsi r a a kọ awọn ọmọ Naijiria ni ọna bi nwọn ti ṣe nṣe awọn ti o fi ndi bata eyiti gbogbo enia nwọ ni oni.

Nipari ọrọ rẹ, Dọkita Otaka sọ wip , o yio ri i daju wipe, aọṣepọ rere wa larin Orilẹ-ede Naijiria ati Czechoslova ia eyiti yio fi ẹsẹ mulẹ d ni -da i loni ti ẹhin ọla.

Minista n dupẹ r upọ lọwọ Aṣoju Ijọba na, o si tun sọ f n un pẹlu wipe, inu on yio dun bi Ijọba Orilẹ ede Czechoslovakia b le wa da awọn le iṣ ola ola silẹ ni Naijiria nibiti nwọn yio gbe le ma ṣe iṣ awọn Awo-tan anran, Rọba, digi ati r ẹ awọ ti nwọn yio ma a fi ṣe bata.

Ọkan ninu awọn enia na ti nwọn ba Aṣoju Ijọba na lọ si odọ Minista ni ọjọ na ni Ọgb ni Vacl v Nosek eniti iṣe Olo i Ile iṣẹ owo fun Ijọba Czechoslvakia ni Naijiria.

Nigbati o si di inu oṣu ti o kọja lọ yi ni Oloye Okotie-Eboh lọ si ilu Prague t o si fi ọwọ si iwe adehun owo na


## Ha! Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile n kiakia o run rẹ si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si d w , iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo ya muyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yo si sun d radara

Ki o ri d ju pa ogun yanmuyanmu o ni erin mẹta yi ti nwọn mu tun o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Oremo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS


### Lati Oju Ewe Kini

fẹ wọ awọn enia kan ni adugbo ti a npe ni Anaye Street, Ilesha i Ọba Adeoshun ri mọto ti o si njona eyiti ko si eniti o le sunmọ inu na t ti mọto na f jona tan patapata.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe ti ko ba jẹ awọn enia kan ti o wa ni adugbo ti mọto n ti njo lo yara tete lọ sinu ile wọn lati lọ bu omi ti nwọn yio fi pa ina na, nwọn ni kọ si ohunti o le ṣe ki moto ayọkẹlẹ ni ma jona pata pata. Awọn Ọlọpa ko ti ri ẹnikẹni mu pe o wa lara awọn to dana sun mọto na

LATI OJU EWE KINI

lati ba nwọn mu oju to ohunti o nṣẹlẹ na ati pe ki nwọn tete fi opin si ofin ki onilegbe ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si agbegbe Ipinle na.

Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 6/12/65